ÌBADAN. 14/5/77 Star Press Ltd.
17 MAY 1977

WEEKS 42&43
Kongi WK 42
13 33 37
Wk 43
11 12 19
Asiko BK WK 42
17 18 19 20
Wk 43
31 38 39 43
Ross Wk 42
20 & 50
WK 43
2 &31

# Imọlẹ Owurọ

ẸSIN ỌRỌ WA: IMỌLẸ DE OKUNKUN PARADA!

SAMCO OF NIGERIA
WK 42
NAP 39 40 41
Perm 23 39 40 41 48
My Address ?
Not nessesary.
Always meet me in
Imole Owuro
Every Saturday

**4 12 32**

Independent Paper Vol. XV NO 797 SATURDAY MAY 14, – FRIDAY MAY 20 1977 10K. (KOBO MẸWA)

# ỌGA ỌLỌPA FUN ỌGA ỌLỌPA LOWO DARAN

ỌGA Ọlọpa kan ti fun Ọga Ọlọpa miran ni riba igba Naira. Riba na ni o si mu Ọga Ọlọpa na gba idajọ ẹwọn ọdun meji.

Ọga Ọlọpa ti o fun Ọga miran lowo ni DSP Anthony Aburime, ẹni ti o si fun ni riba na ni Ọga Ọlọpa ASP Joseph Akinyẹmi.

Awọn afẹsunkanni l'o fi ẹsun kan Ọga Ọlọpa DSP Anthony Aburime pe o gba riba l'ẹnu iṣẹ. Aburime ti a nwi yi ni Ọga awọn Ọlọpa—inu fun agbegbe Ibinni ni Ipinlẹ Bendel.

Irohin sọ pe nwọn pilẹ ti fi ẹsun kan DSP Anthony Aburime pe, ọwọ rẹ ko mọ nibi iwadi ẹsun ipania kan ti o waiye nilu Ibinni ninu ọdun ti o kọja. Nwọn ni Anthony Aburime ni adari iwadi ti awọn Ọtẹlẹmuyẹ nṣe l'ori iwa idigunjale kan ti o ṣẹlẹ ni ilu na, ninu eyi ti Ijoye kan, Oloye Solomon Ogiemwenken padanu ẹmi rẹ.

Awọn afẹsunkanni wa fi ẹsun kan DSP Anthony Aburime pe, o fi abẹtẹlẹ igba Naira fun Ọga Ọlọpa Ọtẹlẹmuyẹ kan ASP Joseph Akinyẹmi ti nwọn ran wa lati Eko lati wadi ẹsun riba gbigba ti nwọn fi kan an l'ori ọrọ ifipajale na.

Awọn afẹsunkanni fi kun un pe ni akoko ti ASP Joseph Akinyẹmi nwadi ẹsun riba ti nwọn fi kan Ọga Ọlọpa DSP Anthony Aburime lọwọ, ni Ọga Ọlọpa na ba fun un ni igba Naira ki o ma baa kọ abajade buburu nipa oun.

Enia mọkanla ni o jẹri nibi ẹjọ pe, Ọga Ọlọpa DSP Anthony Aburime gba abẹtẹlẹ l'akoko ti o nṣe iwadi nipa iwa idigunjale ti o gba ẹmi Oloye Solomon Ogiemwenken.

Ṣugbọn ninu ẹjọ arojare tirẹ, Anthony Aburime sọ pe, oun ko fun Ọga Ọlọpa ASP Joseph Akinyẹmi ni abẹtẹlẹ rara, o ni, "nṣe ni ASP Akinyẹmi ati awọn ọta mi fẹ fi ko ba mi".

LỌỌYA MẸRINDINLỌGBỌN!

Irohin fi ye wa pe, Lọọya mẹrindinlọgbọn l'abẹ aṣaaju Ọgbẹni J.O Sadoh, ni o ngbẹnusọ fun ọdaran na.

Ninu ọrọ wọn fun ile ẹjọ nigba ti Adajọ ile ẹjọ giga na ti kede pe, oun da ọdaran na l'ẹbi ti o si beere lọwọ awọn Agbẹjọro na bi nwọn ni ọrọ lati sọ, nwọn ni awọn ni ọrọ lati sọ.

Ninu ọrọ wọn, awọn agbẹjọro na sọ fun ile ẹjọ pe, ọdaran na ti lo ọdun mọkanlelọgbọn ninu iṣẹ Ọlọpa, bẹẹ ni o si bi ọpọlọpọ ọmọ ti o nilati tọju, awọn si rọ Adajọ ile ẹjọ na lati fi sisanwo itanran kun idajọ rẹ.

IDAJỌ

Ninu idajọ rẹ, Adajọ ile ẹjọ giga na dajọ ni ọjọ kẹwa oṣu yi. Ọlọla Ovie – Whiskey ti iṣe Adajọ Agba Ipinlẹ Bendel sọ pe oun kọ ẹjọ ti ọdaran na ro ati ẹri ti ẹlẹri kanṣoṣo ti o pe jẹ.

Adajọ na sọ pe, awọn afẹsunkanni ti fi idi ẹsun na mulẹ daradara. Ọlọla Ovie–Whiskey fi kun un pe bi ki i ba ṣe pe oun ṣaanu rẹ, oju rẹ ki ba gba to imu ẹlẹdẹ.

Nigbana ni Adajọ na paṣẹ ki Ọga Ọlọpa na, DSP Anthony Aburime lọ san ẹgbẹta Naira (₦600.00) owo itanran tabi ki o lọ fi ẹwọn ọdun meji jura,



ỌGAGUN ADEKUNLE LAWAL
Gomina Ipinlẹ Eko

## Kansilo yari mo Kansilo lowo

DIẸ l'o ku ki ẹṣu tapo si ọrọ awọn Kansilọ Igbimọ Ijọba Ibilẹ Agbegbe Erekuṣu Eko (Lagos Mainland Local Government) ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi nigba ti awọn Kansilọ mọkanla kan ni apa kan ati awọn Kansilọ yoku pẹlu Alaga Kansul na ni apakeji bẹrẹ si i tako ara wọn l'ori yiyan ọmọ Igbimọ na mẹri ti yio ṣoju Kansul na mbi ile iṣẹ meji kan ti Kansul na ni ninu okowo rẹ.

Awọn ile iṣẹ meji na ni City Retreading Services Limited, Lagos ati Luna Park Limited ni Apapa.

Gẹgẹ bi a ti gbọ, nwọn ni mpa yiyan awọn ti

(Woju Ewe Kẹjọ)


## Apprentices Wanted

LEARN to become a successful printer; learn on modern machine with modern tecnique.

Parents, don't waste the time of your fresh Primary Six & Modern III School leavers; send them to learn modern printing, Machine operating and Book-binding from us. Apply personally today.

The Works Manager,
(Imọlẹ Owurọ)
N4/496B Yemẹtu Aladorin,
Ibadan:

# ÌSỌ̀RỌ̀-N'ÍGBÈSÌ...

## IPADE (55)

Lawuyi Ogunniran
ỌOKU l'oni o Alajao mi
Iji Alugbe, baba Kafilatu.
L'ọsẹ t'o kọja l'o sọ ṣiwaju
Pe, b'o ba d'ọsẹ yi
O ni ibeere t'o o beere.
Ọsẹ na l'o pe yi o Alajao mi,
Ajao Alayọ, ọmọ Irioṣẹjẹ
Adeyẹmọ Ọjẹrinde
O ṣehun l'aiye, ọmọ Ejigbọjọ,
Bẹẹ na l'a a wi,
Bẹẹ l'a kuku u bi ni
Ng koi gbagbe rara,
Ma ṣe bi, mo ti gbagbe ọrọ ni
Ng ko gbagbe ọrọ rara
Ng ko ni i ṣalai beere.
Lawuyi Ogunniran
Nṣe ni mo ṣe bi,
Ọbarakosun ti ko ọ n'iye lọ ni
Nitori, Ọbara ko nilaari,
O le ko ọ n'iye lai mọ.
Adeyẹmọ Ọjẹrinde
Irọ ni: a ki i r'afẹfẹ mu,
A ki i r'omi mu
Ko s'ẹni t'o le mu ofo.
Iṣu ki i ta, k'o gbagbe ongo,
Agbado ki i y'ọmọ
K'o gbagbe irukẹrẹ;
A ki i kọle k'a gbagbe ote;
Asunkan ni ti iye;
B'afẹfẹ ba fẹ, inu ẹẹkan a laye,
B'akukọ ba gbọnpa pipi,
Iye inu rẹ a la.
Ọna mẹndilogun ni
Ewe oniyenye ti i luju,
Gbogbo rẹ ni fi i mumi,
Ojumọ ki i mọ ki ẹnu imọ o ma ji.
Eyi ti m• ba bugada, ti mo gbagbe,
Ki ewe iran maa ran mi leti,
K'agbara ojo
Maa gb'orin pade mi,
Nitorina ọmọ Ejigbọjọ,
Iwọ l'o tete yawọ
Mo fẹ bi ọ l'ọrọ tẹlẹ.
Wayi o: Ohun ti mo fẹ bi ọ ni
Pe, njẹ nitootọ ni
Oṣo nbẹ nile aiye?
Njẹ ajẹ enia wa
N'ile duniyan ?
Awọn emere nkọ
At'awọn ti nsaagun pa ni,
Njẹ l'otitọ
Gbogbo wọn wa ni duniyan ?
B'o ba ti ri,
Mo fẹ ki o sọ
Ki ng maa gbọ s'eti;
Mo fẹ ki o sọrọ yi,
Mo fẹ ki o fun mi l'esi l'asiko
Lawuyi Ogunniran
Ajao, ki l'o ri
Ti o fi nbi mi ?
Kini idi ọrọ ti o gbọ
Ti o fi nwadi ọrọ ?
Ṣe, emi jẹ opitan ajẹ ni
Tabi mo jẹ alagbawi awọn
Ti i t'ori jẹ apa,
Ti i t'ẹdọ jẹ ọkan,
Ti i t'idi j'oronro,
Ti i gbe 'wọ fun 'ni jẹ ?
Kini idi ọrọ yi, Baba Kafilatu ?
Adeyẹmọ Ọjẹrinde
O kare l'aiye, ọmọ Ejigbọjọ.
Mo kuku r'idi ọrọ tan
Ki ng to beere ọrọ.
Ki i ṣe pe, mo nbeere lasan,
Ohun ti mo gbọ l'o padi ọrọ.
O pẹ ti mo ti ngbọ
Lat'ẹnu alakọwe pe,
Oṣo ko si, ajẹ ko si,
Oloogun ika k• si,
Gbogbo wọn ni nsọ pe,
Irọ l'ọmọ araiye npa kiri;
Nwọn ni k'a ma gba wọn gbọ,
Nitori, aimọkan ni.
Nwọn ni, alaimọwe enia
Ni nsọ bẹẹ kalẹ.
Ṣugbọn, mo gbọ ni, ng ko gba,
Ng ko gba rara, ọmọ Ejigbọjọ
Nitori, mo fẹ gb'ọrọ ẹnu rẹ
Ki ng to mọ ki l'o yẹ,
Ng ko fẹ tete gbagbọ
L'o jẹ nwa wadi ọrọ.
Lawuyi Ogunniran
Ajao ! Mo gbọ, ọmọ Ajiṣegiri.
Mo gbọ 'di ibeere yi
Ṣugbọn o ko ṣalaye ọrọ.
Bawo l'o ṣe jẹ pe
Emi l'o wa bi leere ọrọ
Bi oṣo nbẹ b'oṣo ko si,
O ri oṣo ri n'ile wa ni
Tabi o r'oloogun ibi ?
Tabi o r'eniyan t'o l'ẹiyẹ
T'o si njẹniyan ?
Adeyẹmọ Ọjẹrinde
Eyi ni ki o ma wi
Ng ko fẹ gbọ rara
Tabi o fẹ fọwọ sọiya
Pe, ara ile nyin ko l'oogun ika?
Ṣe gbogbo agbaagba
T'o wa nile nyin ko l'oogun ibi
Ko si oṣo ninu wọn,
Ko si si ajẹ eniyan ?
O yẹ ki o maa ronu
Ki o to maa sọ 'hun ti o fẹ wi
Mo fẹ ki o maa r'ero t'o kun
Ki o to maa gbe 'ra rẹ gẹgẹ
Nitori: Ng ko r'idile aiye
Ti ko l'eeyan ibi
Atonbọrobọsin agbo ile nyin
T'arugbo ibẹ pọ bi erupẹ.
O l'arugbo nile nyin
O ni ẹ ko l'oṣo n'ile
O l'agba kujẹlẹ n'ile
O ni ẹ ko l'ajẹ eniyan
Ẹ ni abule, ẹ moko ẹgan
O ni, ẹ ko l'ol'oogun ibi?
Nibo l'o ti r'eeyan
T'o n'ile t'o tobi
Ti ko leniyan ika?
Mo fẹ ki o ma ṣi mi gbọ
Ọmọ Ejigbọjọ:
Ng ko bu ọ, ng ko bu ile nyin
Ng ko si fọwọsọiya
Pe, ile nyin ni 'ka l'ọọdẹ
Mo si ti sọ fun ọ
Pe, ohun t'o padi ọrọ ni
Ohun t'alakọwe nro gbogbo
Pe, oṣo ko si, ajẹ ko si,
Ko si s'oloogun ika.
Eyi ni mo fẹ ki o jọwo
Ki o dahun l'ẹsẹ kan
Ki ng le mo
Eyi ti ng o gbagbo nibẹ.


Ogunranti Special Nap

18

28

34

IWE IGBAẸLODE
DARA PUPỌ.
RA TIRẸ NIBẸ
1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agba 20k
2. Kurani ọgọta esu ni ede Yoruba ₦10 Esu kan (50k)
3. Yasin ni Yoruba ati Isawaka 50k
4. Zabura ati Itumọ (₦1)
5 Zabura Yoruba (₦1)
6. Iwe Aiye Akamara (₦1)
7. Iwe Eniaṣoro (₦1) Adedẹwẹ (50k)
8. Iwosan Ajẹbidan Ogun enia dudu (₦6); Kekere (50k)
9. Iwe ala ni nla (₦2)
10. Kekere (50k)
11. Iwe Oogun iwosan (₦2.50) Kekere (75k)
12. Itan Anabi ati Yisa (₦1)
13. English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (50k)

FI OWO ATI STAMP (5k) RANṢẸ SI:

(1) Alufa Yisa Igbaẹlode N2/394a Odo—ye Adeoyọ Rd, P. O. Box 3365, Mapo—Ibadan.



(2) Alufa Igbaẹlode, Mọṣalaṣi Idi. Iṣin St Isalẹ Koto P. O. Box 17. Ilọrin.



WOLI S. I. OWOẸYẸ
Oniwaasu Naa.

## Akẹ́dẹ́ ọ̀nà Iyè

# Olotito ntan lo ninu awon Omo enia (2)

"OLUWA bojuwo lati ọrun wa sara awọn ọmọ enia, lati wo bi ẹnikan wa ti oye ye, ti o si nwa Ọlọrun. Gbogbo wọn ni o si jumọ ya si apakan, nwọn si di eleeri patapata; ko si ẹni ti nṣe rere, ko si ẹnikan.

Gbogbo awọn ti nṣiṣẹ ẹṣẹ ko ha ni imọ? Awọn ẹni ti njẹ enia mi bi ẹni njeun, nwọn ko si kepe Oluwa. Nibẹ ni ẹru ba wọn gidigidi; nitori Ọlọrun nbẹ ninu iran olododo ": Orin Dafidi 14; 2 – 5.

Oniruuru iwa buburu gbogbo ni o wa lọwọ awọn ọmọ enia: ole, igara, opurọ, ipania, oṣo, ajẹ, elebọlogun ati bẹẹbẹẹ lọ l'o kun inu wọn.

Ṣugbọn lati ọjọ ti mo ti de aiye yi, ng ko tii ri ile iṣẹ Ọlọpa ti i mu oṣo ati ajẹ, bẹẹ ni iwa buburu ti oṣo ati ajẹ nhu ninu aiye buru jọjọ. Bi ọlọgbọn, oloye ati onimọ ijinlẹ ti wa ninu iṣẹ gbogbo ni nkan wọnyi wa ninu oṣo ati ajẹ pẹlu. Ọjọgbọn ati onimọ ijinlẹ wa ninu wọn.

Ṣugbọn, kini oṣo ati ajẹ fi imọ ijinlẹ wọn ṣe? Nwọn ti yapa kuro ninu ifẹ Ọlọrun. Awọn ni ọta iwaasu ododo, awọn ni nwọn maa nwọnu enia lati ṣe ohun gbogbo ti o ba lodi si ifẹ Ọlọrun.

Awọn ni nwọn maa njẹ ki o ye enia pe, ẹni ti ko ba juba "alaiye" ko le ṣe ohun rere ninu aiye bẹẹ ni awọn kanna ni ọta "alaiye" nitoripe bi o ti wu ki oṣo tabi ajẹ fẹran enia to; nwọn ko le jẹ ki ohun rere pẹ lọwọ enia.

Njẹ iwọ mọ bi oore oṣo ati ajẹ ti ri? Oore buburu ni. Nwọn le maa ṣe baba l'oore ki nwọn si maa pa a l'ọmọ jẹ. Bi nwọn ba fi ẹnu eke ko enia l'ẹnu l'oru; bi ilẹ ba mọ, gbogbo ẹni ti o ti fẹran onitọhun tẹlẹ a si di ọta rẹ.

Awọn ni nwọn maa npa kadara enia da si aidara, Awọn ni nwọn maa nba enia jagun l'oju oorun ati l'oju ala awọn ni nwọn maa nba; ayọ enia jẹ. Nwọn korira otitọ nwọn a si maa gbogunti ododo.

Awọn enia buburu ati enia ẹjẹ wọnyi pọ ninu aiye; awọn olotitọ ntan lọ; awọn olododo si ndasẹ laarin awọn ọmọ enia.

Awọn oṣo, ajẹ ati enia buburu aiye wọnyi a maa lo onirnuru ọna ati enia lati da ilu, ile ru ati lati ba enia jagun. Awọn enia ti nwọn nlo ni oniyemeji.

Iru wọn ni o maa nṣiyemeji pe "Njẹ Ọlọrun ha wa nitootọ?" Iru wọn l'o maa npariwo Jesu ninu ile isin ṣugbọn ti nwọn maa nṣẹ Orukọ Jesu Kristi ni ita; ani, awọn ti a maa nfun ni ounjẹ ti nwọn si maa ngba pe, ẹni ti o fun wọn ni ounjẹ gan—an ni Ọlọrun wọn lẹsẹkẹsẹ lai ronu pe, Ọlọrun ni O ran ẹni ti o nṣe iranlọwọ na fun wọn si wọn.

Awọn oṣo ati ajẹ wọnyi ki i duro si ibikan ninu aiye, nṣe ni nwọn maa nrin kaakiri aiye lati ṣiṣẹ ibi wọn. Nwọn a maa ti orilẹede de orilẹ-ede, gbogbo imọ lati wọle onile lai ṣilẹkun ni o si kun inu wọn ati ki a maa pa enia ti nbẹ l'aaye jẹ lai ku.

Awọn ajẹ ni ọgbọn ṣugbọn fun ibi ni; nwọn ni imọ ijinlẹ ṣugbọn ki i ṣe fun ifẹ Ọlọrun. Nwọn a maa sọ pe, ẹnikan ko le gba adura fun awọn nitori awọn mọ baba awọn.

Orişirişi ọgbọn ti a fi le yi enia pada si keferi ni nbẹ ninu wọn. Nwọn a maa sọ ọkọ di ọta aya rẹ. Nwọn ti fi iwa okunkun wọn le ọpọ obinrin kuro ni ile ọkọ rẹ; nwọn ti fẹ ọkọ ọlọkọ fun ọmọge miran.

Ọpọ ọmọ ile iwe ni nwọn ti paarọ ori rẹ; awọn ni nwọn maa nfi eke ṣe ọmọ ọdọ olodo- Nwọn dara l'oju ṣugbọn inu wọn, kiki ibi ni.

Ẹni okunkun inu aiye yi korira imọlẹ pupọ ati iṣẹ ododo. Bi enia nnawo pupọ, nwọn le sọ pe, nṣe ni oluwarẹ ṣẹṣọ; bi ko si nawo, nwọn a pe e ni ahun. Bi enia nṣiṣẹ iwosan nipa agbara Jesu, nwọn a ni afọṣẹ ni oluwarẹ nlo.

Bayi ni awọn ẹni okunkun aiye yi ri ninu iran wọn. Awọn ni nwọn ko idaamu ati wahala wọ inu aiye nipa agbara okunkun wọn. Nwọn ni ọgbọn ṣugbọn nwọn ko lo o fun iṣẹ otitọ. Idi niyi ti Orin Dafidi 14; ẹsẹ 4 fi ntọka si i pe "Gbogbo awọn ti nṣiṣẹ ẹṣẹ ko ha ni imọ?....". Nwọn ni imọ ṣugbọn imọ na ni nwọn fi nkọju ija si Ọlọrun Ẹlẹda wọn.

## Lati Owo Woli S. I. Owoeye

### ADURA

Njẹ gbogbo ẹnyin enia ti njẹ enia bi ẹni jẹ iṣu: L'orukọ Ọlọrun Alaaye t'O ni ilẹ ati ẹkun rẹ ni mo ke ni ohun rara l'oni pe: Ogun Ọrun! Ogun Ọrun! sọkalẹ wa l'Orukọ Oluwa ki o wa pa awọn ọta Ọrọ Ọlọrun ti nwọn ndọdẹ mi run ninu aiye ki ng le maa jẹri si iṣẹ otitọ ti Ọmọ Rẹ Jesu Kristi ṣe l'aiye k'a ma baa ṣegbe tan lai ati lailai, Aamin.


**NIGERIA NEW STATES CO.**

Jẹ atẹwe asiko. Bi o ba fẹ tẹ oniruuru iwe Kalenda, Almanak ati bẹẹbẹ lọ, Ile Iṣẹ wa wa ni:

18, Ọdunlami Street,
Phone 27017, Lagos.



**IWE ỌRỌ ỌLỌRUN.**

Fun anfani ẹnyin ti o ṣoro fun lati ri iwe mi yi ra ni ọkookan, mo ti ṣeto lati maa fi apapọ iwe na ṣọwọ si nyin ni aadọta Kọbọ (50k) pere.

1. ADURA AIYERAIYE
2. IBANIWI OLUWA
3. KINI ILE AIYE ṢE BAJẸ?
4. Ẹ JOWO ARA NYIN FUN OLUWA

Bi o ba ti fi Postal Order 50k ṣọwọ si mi, ng o fi apapọ iwe na ṣọwọ si ọ lagbara Oluwa, Fi owo ranṣẹ si:

Woli S. I. Owoẹyẹ
Box 1206,
Ibadan.

# Ẹ gbọ t'emi

## Ibaje lasan ni

OLOOTU,

LAIPẸ yi ni onkawe kan nbeere lowo Olootu Imolẹ Owuro, iru ẹni ti awon enia maa npe ni olowo ojiji.

Ninu idahun ti Olootu fun onkawe na ni Olootu ti so pe, iru awon enia kan ti nwon di olowo ojiji, ti awon enia ko r'idi bi nwon ṣe l'owo, ni awon enia maa npe ni olowo ojiji.

Mo fẹ ki Olootu ati gbogbo onkawe gba pe, olowo ni olowo njẹ, ot¬oto si ni ona ti olukuluku yio gba dide. Nitorina, bi Ọlorun ba gbe enia kan ga, ki a gba pe o ga, ki a ma maa ba a l'orukojẹ nitori ilara. Nitorina, ibajẹ lasan ni eyi jẹ lati maa pe enia kan ni "olowo ojiji."

Ajani Baba Kudi,
Eko

## K'a rin k'a po

OLOOTU,

O pẹ ti mo ti maa ngbo owe kan ti awon Yoruba maa npa pe: "K'a rin, k'a po, yiyẹ ni i yẹ ni"

Ohun ti mo wa fẹ beere lowo Olootu ni pe, ṣe l'aiye ijoun ni tabi owe na ṣi wulo l'aiye ode oni? Nitori bi enia ba rin papo jale l'ode oni, nwon yio dijo kẹhin si agba ni.

Emi ni,
Aransi Ṣeu,
Iwo

Akiyesi

Ọrẹ wa Aransi,

Bi owe na ti wulo lati aiye ijoun na ni o wulo l'ode oni, ṣugbon gẹgẹ bi enia ba ti lo owe na *si* ni.

Ti ẹlomiran ba npa owe na l'ode oni, o le so pe: "K'a rin k'a po, yiye ni i yẹ ni; "ṣugbon bi i ti ona ọrun kọ". Ẹlom ran le so pe, "bi i ti ẹlẹwon kọ".

Ni kukuru, iha ti olukuluku ba kọ si owe ni owe yio kọ si i.

—OLOOTU.

## Iwaasu Owoeye fakiki

OLOOTU,

GBA mi l'aye lati kan saara si Woli S. I. Owoẹyẹ ti iṣe Oniwaasu wa atata, ẹni ti o maa nfi iwaasu bọ wa ninu Imọlẹ Owurọ.

A ngbadun iwaasu rẹ pupọ paapaa itan kukuru ti o so labẹ iwaasu ti akole rẹ jẹ "A o rẹ agberaga silẹ."

Ọrọ iyebiye ni Oniwaasu na fi nbo awa onkawe Imolẹ Owuro. Ọlorun yio maa wa pẹlu Woli wa na.

Emi ni,
Tunde,
Eko

## Akiyesi fun Onkawe

EYI ni lati kede fun gbogbo onkawe ti o ba nkowe "Ẹ GBỌ TEMI" si wa fun titẹjade, pe, ẹ gbodo maa kọ orukọ nyin ati ti Adirẹsi nyin tooto si ara iwe na.

Nitori pe, opolopo iwe ni a nri gba lati odo onkawe ti awon ti o ko won ko fi Adirẹsi won tooto si i l'ara.

Bakanna ni ẹlomiran yio kowe si wa lati ilu Eko, ṣugbon ti yio fi Adirẹsi awuruju si i pe lati "Bukuru" tabi "Ogbomoṣo" ni oun ti ko o.

Iru iwa yi poju lowo awon ti nkowe si wa, eyi ti o lodi si ilana iṣẹ wa.

A fe ki o ye olukuluku pe bi o ti wu ki oro inu iwe ti ẹ ko le to, a o fi tayotayo gba a yẹwo, a o si tẹ ẹ jade bi • ba yẹ, koda bi o jẹ pe awa paapaa ni oro na ba wi.

Nitorina bi a ba ri iwe kan gba ti ko tẹle ilana iṣẹ wa tabi ti ko ba mu ogbon dani; tabi ti ko ba le ṣanfani fun onkawe tabi ti oro inu rẹ ba lodi si ofin, a ko ni i tẹ ẹ jade.

—OLOOTU

FOR ALL YOUR

Electronics

Fans, Cookers, Radio sets, T.V.& Colour T.V. sets, coolers etc: at resonable prices

PATRONIZE

Aiyedetisola

Commercial

Electrical

Store:

N27 I.C.C STALL
AGODI GATE
IBADAN

# Ara Iregba nfe Iranlowo

AWỌN enia ilu Irẹgba ati agbegbe rẹ labẹ ijoba ibilẹ ilu Ogbomoṣo ti kesi ijoba ibilẹ Ogbomoṣo lati ba awon fi wọrọkọ ṣe ada nipa fifi owo ati awon ohun elo ijoba ibilẹ na ran awon lowo nipa ile igboogun ati ti ile abiye (Dispensary / Maternity Centre) eyi ti awon nko lowolowo ni ilu Irẹgba pẹlu oogun oju ara awon.

Agbẹnuso kan fun awon enia na, Ọgbẹni James Oyewo Oyekunle l'o pe ipe na lẹhin ipade kan ti awon enia na se nilu Iregba laipe yi.

Ọgbẹni Oyekunle so pe, iranlowo na ṣe pataki lopolopo nitoripe nibi ti iṣẹ na de duro bayi, yio jẹ alebu gidi ati pe, ofo onile ofo alejo ni yio jẹ ti o baṣe bẹẹ duro.

O ṣe alaye siwaju si i pe, o to nkan bi odun meji sẹhin ti awon ti bẹrẹ iṣẹ na ṣugbon ti owo ta awon igbimo ti nmojuto eto na nlo lowo eyi ti o mu ki iṣẹ na wa bi o se wa bayi.

Ọgbẹni Oyekunle ni ero awon lati ko ile igboogun ati ti abiye na ni lati din iṣoro ati wahala awon enia lagbegbe na ku paapaa julo awon alabiyamo ati abaraeji obinrin.

O ni nkan bi ẹẹdẹgbaaje Naira (N15,000) ni awọn ro pe yio pari iṣẹ na nigbati awon ko bẹrẹ, ṣugbon bi ode ṣe ri bayi, ko ṣai ni fẹrẹ to nkan bi ilopo meji. O ro Ijoba Ibilẹ lati ran won lowo, o si ṣe ileri pe, ti Kansul na l'awon nṣe.

# Alebiosu se bebe

IDUNNU ṣubu lu ayo fun idile Laoye, Ode Arẹmo nilu Ogbomoṣo lai pẹ yi nigbati okan ninu awon omo won, Ọgbẹni G. M. Lawal Alebiosu pẹlu meji ninu awon iyawo rẹ ti Mẹka de ti o ṣi ile titun ti o si ra moto titun pelu.

Ni ojo Ẹti ti iṣe ojo kẹjo oṣu kẹrin odun yi ni nwon ṣe akanṣe idupẹ ni Moṣalaṣi Jimo Ogbomoṣo. Ni ojo yi kanna ni ayẹyẹ ṣiṣi ile gareti ti a wi yi na waiye nibi ti awon sanmorisanmori ti fi aṣo lesi olowo iyebiye ba awon tokotaya, Alhaji ati Alhaja titun na ṣe ariya.

Diẹ ti aye wa fun lati daruko l'ara awon alabaṣeye ojo na ni: W. Saka Aolalubarika-pupọpupo, Alhaji R. A. Sadiku Jẹjelaiyenfẹ, Oluranti Oyewo, Oyewo Oyekunle, Ọmo oba Okunlola Ọlanrewaju, Olujide Akande, Akanbi Ikarẹ, Iyaafin Agnes Saka, Mojoyinola Sadiku, Inawo ojo na kọyọyọ.

# Asipa Oyo sajodun Oye

AṢIPA ilu Ọyọ, Oloye Amuda Afolabi Okunade Olorunkosebi, ti kan saara si Ijoba Ologun Apapọ Naijiria fun ipo iyi ati ẹyẹ ti o nto awon Ọba ati Ijoye ilẹ wa si ni igbagbogbo.

Nigba ti Oloye na nba awọn ara Isalẹ-Ọyọ soro laipẹ yi ni akoko a ẹyẹ ajodun odun kinni ti o di Aṣipa Ọyọ, ni o soro na. Ọsẹ kan gbako l'o fi ṣe ayẹyẹ na.

Aṣipa na fi kun un pe, Ijoba Ologun Naijiria fi ifẹ ti nwon ni si Ọba ati Ijoye ilẹ wa han nipa mimu ki igbesi aiye rọ won l'orun si i, o si kesi awon Ọba ati Ijoye na lati fowosowopo pẹlu Ijoba na.

Nigbana ni Oloye Aṣipa dupẹ lowo awon enia na fun ifẹ ti nwon ni si i ati atilẹhin wọn lati odun kan sẹhin ti oun ti joye.

L'akoko ayẹyẹ na, opo ibi patakipataki nilu Ọyọ ni Oloye na de, o si ṣetutu fun alaafia ati ifokanbalẹ laarin ilu.

## 12: 18: 25: 39:

## Nap: 14 27 41


## Wanted

APPRENTICES and advanced apprentices are wanted in our Printing Section.

Remuneration is very attractive. Bring your application by hand to the Manager:

NIGERIA NEW STATES CO:
18, Ọdunlami Street,
Lagos.

## Yasin ati Isawaka

EYI ni lati kede fun ẹnyin onibara wa ti ẹ ti nkowe si wa lati ọjọ pipẹ pe, a ti ni Yaasin ati Isawaka ni ede Yoruba ati Wutuba rẹ.

Adura pataki ni fun Musulumi. 50k ni Ẹyokan, N2. ni Dosinni rẹ.

Tete fi owo ranṣẹ si:-

Alufaa Igbaẹlode
N2/394A Odoiye
Adeoyo Rd,
P. O. Box 3365
Mapo, Ibadan

(2) Alufaa Igbaẹlode
Moṣalaṣi Idi Iṣin St;
Iṣale Koto,
P. O. Box 17
Ilorin

KEREO

GBOGBO - ENIA! fun

•Ipolowo ọja ati Ikede,
•Akiyesi ati Itufọ,
•Iranti oku ati Ikede Ariya,
•Ikilọ ati bẹbẹ lọ;
•Tabi Almanak ati Kalẹnda titẹ.

DARAPỌ PẸLU AWỌN ỌLỌGBỌN ENIA TI O NṢEE SI INU (IMỌLẸ OWURỌ) TI O GBAJUMỌ KARI AIYE. OWO TI A NGBA KOPỌ, SA KỌWE TABI KI O WA RI:-

Advertisement Manager:

IMỌLẸ OWURỌ
N4/496B YEMETU ALADỌRIN,
P.M.B. 5230, IBADAN.

# Agbéyèwò ohun titun t'o gbode

REKODU, IWE, ORIN, ARE-IDARAYA.

# Adewole kilo fun Onisokuso



ADEWOLE ANIMAṢAHUN
(Onilu—Ọla)

NINU awo ti gbajumọ Onilu ara nni, Adewọle Animaṣahun (Onilu ọla) ati Ẹgbẹ Alapala rẹ ṣẹṣẹ ṣe ti awọn enia ti o ni ifẹ si are apala ti bẹrẹsi dura bi akara gbigbona bayi, ni o ti kilọ fun awọn kan ti o pe ni onisọkusọ ati awọn onirohin ahesọ pe ki nwọn ṣọra wọn.

Adewọle Animaṣa hun sọ pe, irọ ni ọrọ kan ti nwọn nsọ kiri pe nwọn ti gbe mọto oun salọ.

O ni irọ ni nwọn npa, nki iṣe mọto ti oun ni nwọn jigbe. O ni "Ole-ti o ba ja ti o gbe kakaki Ọba, nibo ni yio ti fọn ọn ?"

Nitorina, Oniluọla wa kilọ fun awọn Abanijẹ enia, ki nwọn lọ ṣiwọ ninu iwa ibajẹ.

Ninu awo titun yi, gbankọgbi owe ati ijinlẹ Yoruba ti o njade lati inu ilu Adewọle ko ṣee fi ẹnu sọ.

Awo na ti Ile—Iṣẹ HASBUNALAU RECORDS gbe jade ti Nọnba rẹ jẹ HRC 7 ti o jẹ ẹlẹẹkeji (Vol. 2) ti ẹgbẹ Adewọle yio ṣe lẹhin ti a da ẹgbẹ Alapala na silẹ, fi han araiye pe, Ọga ni nwọn jẹ ninu are apala ti o ba ode mu.

Nipa ti orin, Animaṣahun ti o jẹ Ọga Olorin na nkọ kisa l'orin, awọn elegbe na si mọ iṣẹ wọn ni iṣẹ. Orin aladun ti o mu ọgbọn dani, ti o si wu ni lori, ti o dun lo lawujọ ati Nasia atata to ṣe e kọgbọn ni o kun inu awo na.

Ni ti faaji ti o ga lọla, awo na ko ṣe e fi ọwọ rọ ti sẹhin nigba ti o ba di pe enia fe ṣẹ nkanẹyẹ bi ikomo, igbeyawo isinku ati bẹẹbẹẹ lo, ni enia yio to gbadun awo na ju nitori ti nwọn ba bẹrẹ si i tẹ awo na fun awọn alabaṣeyẹ, ajolaagun ni nwọn yio maa jo nitori Adewọle lu kisa ilu sinu awo na.

Bi a ko ba ni i purọ, Adewọle Animaṣahun (Oniluọla) ati ẹgbẹ alapala rẹ dan nkan wo ninu awo ti mo nsọrọ rẹ yi. Irohin ko to afetigbọ, afetigbọ ko to ki a ri ti ara ẹni, ni ọrọ awo na jẹ.

Ki a sọ otitọ, Ile-Iṣẹ HASBUNALAU RECORDS ti • tẹ awo na ṣiṣẹ t'o jọju lori awon na ati paali rẹ. Irinṣẹigbalode (Stereo) a-dun gbọseti ti o ni alope ni nwọn fi ṣe awo na. Paali rẹ kọyọyọ, aworan ara re ti iṣe ti Adewọle Onilu-ọla ti o joko pẹlu agbada leesi nla ati ilu lọwọ kamama, ti odikeji si jẹ ti oun pẹlu Olorin rẹ ti nje Animaṣahun ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ han ketekete.

Koṣeemani ni awo na jẹ fun gbogbo enia ti o ba nifẹ si awo ti o kọnilogbọn ti o si mu inu dun. Ẹ le ri awo na ra kaakiri ile itaja rẹkọọdu adugbo yin tabi taara lọdọ:

HASBUNALAU TRADING CO;

561 L. E. D. B. Shop,

Balogun St:

Eko Tel. 57686.

# Aiyederu Adiyeloja f'ewon jura

ILE-ẸJỌ Ibilẹ kan nilu Ogbomọṣọ labẹ aga Oloye Samuel Ojo ti ju ọkunrin lebira kan Adebisi Abifarin, ẹni ọdun marundinlogoji si ẹwọn oṣu mẹrin tabi ki o lọ san aadọrun Naira (₦90.00) owo itanran si apo Ijọba.

Ẹsun ti awọn afẹsunkanni ka si ọdaran na l'ọrun ti o wa sọ ọ di ero ẹwọn yi ni pe o pe ara rẹ ni oṣiṣẹ Adiyelọja nigba ti ki i ṣe bẹẹ.

Nigba ti ẹjọ na bẹrẹ nile ẹjọ, ọkunrin onisẹ panapana kan, Ọgbẹni A. Adebọ sọ fun ile ẹjọ pe, ninu ile ọti Arabinrin C. A. Adigun ẹni ti awọn dijọ ngbe ile kanna ni Adebisi Abifarin ti da ẹṣẹ na.

Ọgbẹni Adebọ fi kun un pe, Arabinrin C.A. Adigun l'o fi to oun leti pe ọkunrin kan pe ara rẹ ni Adiyelọja fun oun. O ni nihin ni oun ti pe e tẹ, ti oun si beere iwe aṣẹ rẹ ti o le fi han pe nitootọ ni o jẹ bẹẹ, ni o ba fi ere gee. O ni nibi ti o ti nsa lọ ni awọn ti nkigbe "Ole ! Ole !" le e l'ori ki awọn aladugbo to ba awọn mu un ti o si ṣe bẹẹ di ero ile iṣẹ awọn Ọlọpa.

Bakanna ni Arabinrin C.A. Adigun jẹri nile ẹjọ. O ni awọn ṣe arufin na ni alejo ninu ile ọti oun ki awo to ya mọ ọn l'ori.

Ninu ẹjọ tirẹ nile ẹjọ na ọdaran na, Adebisi Abifarin ẹni ti o sọ pe lebira ni oun iṣe, sọ pe ou- jẹbi ẹsun na ṣugbọn o bẹbẹ pe ki ile ẹjọ ṣiju aanu wo oun.

Ṣugbọn ninu idajọ rẹ, Adajọ ile ẹjọ na, Oloye S. O. Ojo ṣe apejuwe ọdaran na gẹgẹ bi onijibiti alọnilọwọgba ti ko yẹ ki o maa gbe aarin ọmọluabi enia Adajọ na sọ pe, oun da a l'ẹbi ẹṣẹ na, ki o lọ san aadọrun Naira owo itanran tabi ki o lọ fi ẹwọn oṣu mẹrin jura

# Oladosu gbe Oluyemi n'iyawo

(Lati Oju Ewe Keji)
wo ṣẹlẹ ni ile ọkọ iyawo ni Alafara Atipẹ nibi ti ẹlẹgbẹjẹgbẹ, ẹbi ọrẹ, ẹgbẹ Onipako, Ẹgbẹ Ajihinrere l'ọkunrinlobinrin pejupesẹ si ati Ẹgbẹ ọmọ Ile Ariwọnmasa, ti iṣe ile ọkọ iyawo wa pẹlu.

**Oriola nap**
**17 23 44 50**

**Rocky Nap**
**10 16 20 46**

**Ejiwumi Nap**
***8 19 26 48***

**12**

**38**

**48**

# 'Ajayi sa Olopa pa ni Ilesa'
## —Afesunkanni

AWỌN afesunkanni ti mu ọkunrin ẹni ọdun marundinlaadọta kan, Adetunji Ajayi lọ sile ẹjọ Chief Magistrate ilu Ilẹṣa lati koju ẹsun ipania.

Awọn afesunkanni sọ fun ile ẹjọ na ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ojọ kọkanla oṣu yi ti nwọn mu ọdaran na wa sile ẹjọ pe, ni ipari ọse t o kọja ni o fi ada ṣa ọkunrin Ọlọpa kan, Ọgbẹni Adio Ajọbọ pa ni adugbo Isona ni ilu Ilẹṣa t'oun t'aṣọ l'ọrun.

Gẹgẹ bi irohin ti wi, nwọn ni nigbati awọn Ọlọpa Ilẹṣa gbọ ẹsun pe ọdaran na nhalẹ pe oun yio pa aladugbo rẹ kan, ni nwọn ba ran Ọlọpa oloogbe na lat lọ pe Adetunji Ajayi wa.

Irohin fi kun un pe ṣugbọn dide ti Ọlọpa na debe gẹgẹ bi ẹsun ti nwọn fi kan an, nwọn ni nṣe ni Ajayi da ada bo Ọlọpa na ti o si pa a ju silẹ ni apafọn.

Iwadi awọn Ọlọpa si nlọ lọwọ l'ori iṣẹlẹ na gẹgẹ bi a ti gbọ.

# Omo be iya re lori

IROHIN fi ye wa pe, ọkunrin kan ti be iya rẹ l'ori ni Ibadan ati pe, ọwọ ti tẹẹ ni adugbo Kudẹti nilu Ibadan nibi ti nw n sọ pe o ti nfẹ gbe oku iya re na sinu odo Kudẹ , Oruk obinrin na ni Tinukẹ Agbeke.

A ko tii gbọ irohin ju bayi lọ l'ori iṣẹlẹ na pẹaṣ a l'ori ki l'o fa a ati iri ti ọrọ na de duro.

*Bakanna ni irohin miran sọ pe ọkunrin Ṣọja kan ni ilu Lanlate ti fi ada ṣa Oloye Eesuọla Aarẹago pa nilu Lanlatẹ ni agbegbe Ibarapa.

Irohin sọ pe, Ṣ ja na l'o halẹ mọ iyawo rẹ pe oun yio pa a nigba ti aaw kan bẹsilẹ laarin wọn.

A gbọ pe nigba ti iyawo Ṣọja na woye pe ọrọ nlọ lodilodi, ni o ba f'ere ge e; o si kibosi tọ Oloye na lọ.

Irohin so pe nihin ni Oloye na ti to Ṣoja na lo, ṣugbon kaka ki o ṣalaye oro fun Baba Oloye, nṣe ni o fi ada ṣa baba Oloye na pa ju sile.

Siwaju si i, irohih so pe, diẹ l'o ku ki Ojiṣẹ Olorun kan ti o wa lati da si oro na fara kọ irin l'ọdọ Ṣoja na.

# Kansilo ati Kansilo

(Lati Oju Ewe Kinni) nw n yan ninu ọmọ Igbimọ na ni awọn mọkanla ninu aw n Kansilọ na fi yari ti nwọn si bẹrẹ si i tako Alagba ati awon yoku pe, awon ko faramo bi eto ipade ojo na ti lo.

Nihin, gẹgẹ bi irohin ti wi, ni apa kinni–keji ti bẹrẹ si i soro si ara wọn burukuburuku ti nwọn ko si roju maa ba eto yoku lọ mọ.

Gẹgẹ bi a ti gbọ nwon ni nigba ti Alaga ati awon ti nṣe tirẹ kojalẹ lati ṣe ifẹ awon onitohun, ni nwon ba binu jade kuro ninu ipade na.

Irohin fi kun un pe lẹhin ti nwọn jade sode tan ni ọkan ninu wọn, Ọgbẹni S. A. Animaṣahun fi ẹsun kan awọn kan ninu awọn Kansilọ ẹlẹgbẹ rẹ gẹgẹ bi ẹni ti o di "ẹgbẹ tẹkto" kan silẹ ninu Kansul na. O ni awọn Kansilọ ti oun wi na jẹ ọmọ ẹgbẹ oselu kan ti Ijọba logun ti fi ofin de.

O ni ọrọ yiyan aṣoju ti a nwi yi l'o mu ki ọrọ na kọ di mimọ si araiye ni; o ni awọn enia na ko ṣẹṣẹ bẹrẹ iru iwa "adanikanṣe" bẹẹ.

Siwaju si i, Ọgbẹni Animaṣahun sọ pe gẹgẹ bi awọn ṣe ri i, "ohun ti nwọn nfọ fun fere ni fere nfọ jade ni ọrọ na jẹ - awọn enia kan ti o wa l'ode ni o ndari wọn."

Ni ipari, Ọgbẹni Animaṣahun sọ pe, gbogbo ẹni ti o ba ti nṣe ti Alaga tabi ti o wa ninu "ẹgbẹ tẹkoto" nikan ni nwọn le yan si ipo. O ni ki iru iwa bẹẹ le de opin ni o mu ki awọn pariwo sita, oun l'o si mu ki awọn binu jade ninu ipade Igbimọ na pẹlu.


# OLORIRE O! OLORIRE O!

AWA ẸGBẸ ONIṢOWO ONIṢẸ ẸRỌ TI NJẸ

## WESTERN NIGERIAN TECHNICAL COMPANY LTD

TI TUN GBE ERO ARAMỌNDA KAN DE. ERỌ NA NI A NPE NI



## Solo Lawn Mower (₦266.00)

(EYI NI ẸRỌ TI A FI NGEKO)

Meji iru ẹrọ yi ko si rara
Ni ilẹ Naijiria.
Bi oko ti le wu
Ki o kun tabi pọ to
Ko jẹ nkankan l'oju ẹrọ na,
Ni kiakia ni yio pari rẹ.
Iwọ ti o ni ọgba l'ayika ile rẹ,
Ati ẹnyin alaṣẹ ile iwe,
Ẹrọ yi ni ki ẹ maa lo.
O dun i geko pupọ,
O si ni alopẹ.
Owo ẹrọ na ko pọ rara
₦266.00 pere ni.
Tete wa ra tirẹ ni:

## Western Nigerian Technical Company Limited

P.M. B. 5148: PHONE 22361/2
DUGBẸ ONIMATIRẸSI, IBADAN.

WENTEC 1955


Printed and published by the People's Star Press Limited, N4/4968 Yemetu Aladorin P. M. B. 5230, Ibadan. Olootu (Editor) Lawuyi Ogunniran, 14303, Aperin Adekile Ibadan. Lagos Office 18, Odunlami St, Phone 27017.